William Bascom, Director
Museum of Anthropology
University of California
Berkeley 4, California

William R. Bascom
Northwestern University

# IMỌRAN FUN AWỌN IYA

NIPA

## "BI O TI YẸ KI A MA FI ONJẸ FUN ỌMỌ LẸHIN TI O BA TI JAYAN TAN."

Lati Ọwọ MISS B. SKERRIT,
*Sister-in-charge Infant Welfare Clinics.*

LATI INU IWE ETO TI A ṢE FUN ỌSẸ ILERA NI EKO NI 1933

*O ha mọ pe onjẹ jẹ ọkan ninu awọn ohun ti o ṣe pataki julọ ninu aiye ọmọde bi?*

*Onjẹ ni imu ọmọde dagba, ti si isọ ọ di ọkọnrin tabi obirin ti o lokun.*

Fifun ọmọde li onjẹ ti kò ba inu rẹ mu, ajẹju tabi aijẹ orişi onjẹ kan tó, tabi lati mā jẹ onjẹ ti a ko sè daradara ni imā mu aisan wá. Nitorina, o yẹ ki olukuluku iya kọ, ki o si mọ bi a ti fun ọmọde li onjẹ li ọna daradara.

*O ha mọ pe o yẹ ki a ma ja ọmọde li ẹnu ọmu, nigbati o ba di ọmọ oşu mẹsan bi?*

Li akoko yi, wàra inu ọmú iya ko tun lagbara mọ, ko si to nkan mọ. Ọmọde a si bẹrẹ si ifẹ lati mā jẹ oniruru onjẹ. Bi a ba jẹki ọmọde mu ọmú ju bi o ti yẹ lọ, yio bẹrẹ si şaisan, kẹrẹkẹrẹ yio si bẹrẹ si rù. *Ma ja ọmọ rẹ lẹnu ọmu diẹdiẹ*, şugbọn kọ bère imọran dokita şāju, tabi imọran awọn obirin ti ntọju awọn abiyamọ.

Igba pupọ li o jẹ ohun işoro lati mọ iru onjẹ ti o yẹ ki a mā fun ọmọ larin oşu mẹsan ati ọdun meji. O kere pupọ ni gbogbo akoko yi lati le jẹ onjẹ ti awọn agba njẹ. Awọn imọran atẹle wọnyi le jẹ iranlọwọ fun ọ lati le wá onjẹ ti o dara fun ọmọ rẹ.

*Ma ranti awọn ofin iyebiye wọnyi: Ma ri pe ọtọ li a nse onjẹ fun ọmọde nigbagbogbo.*

A ko gbọdọ fun u ni *onjẹ ti awọn agba njẹ*, ti o ni epo *pupọ* ati ata ninu; a le fi ata nla diẹ si i, ki a si ma fi kun u, bi ọmọde na ba ti ndagba si.

Ki a mā fun u li omi awọn nkan wọnyi mu nigbati nwọn ba ti to ọmọ oşu mẹfa: omi orombo,